17/8/74
IBADAN
21 AUG 1974

Kongi Nap WK 3
2 5 11

ASIKO Bks Wk 3
12, 15, 24, 32,

ROSS BKS Wk 3
15x27

Imọlẹ Owuro

ṣin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draw in Wk 4 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekalẹ Ibadan.
See him with ₦5 before 2 p. m. on Saturday.
NAP WITH ₦10
2, 8, 9, 39

Independent Paper VOL. XIII No 652 SATURDAY AUGUST 17 – FRIDAY AUGUST 23, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN)

# ỌLỌṢA FI EṢU ṢE ARAA WỌN NI ONIṢA

IROHIN lati Ipinlẹ Aaringungun Ila-Oorun fi ye wa pe awọn ọlọṣa kan ti fi eṣu ṣe araa won ni akoko ti nwọn nfọ ile lọwọ ni ilu kan lẹba Onişa. Ni ipari ọsẹ ti o kọja ni iṣẹlẹ na ṣẹ.

A gbọ pe ni ilu Ogbe-Umuonicha gan-an ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ. Irohin sọ pe awọn ọlọṣa kan ni nwọn dira ogun wọ ilu na lọ ti nwọn si fọ ile mẹta ni ẹiyẹ ko sọka.

Irohin sọ pe lẹhin eyi ni nwọn wọ ile ọkunrin kan; nwọn ji ọkunrin na l'oju oorun, nwọn si paṣẹ fun un pe ki o bọ si gbangba ode.

Irohin sọ pe nigbati ọkunrin na bọ sode tan ni nwọn sọ fun un pe awọn wa lati kole rẹ ni, nitorina, ki o dọbalẹ gbalaja silẹ, ki o si dojubolẹ titi awọn yio fi kole na tan. Nigbana ni nwọn fi ọkan ninu wọn sọ ọkunrin onile na ki o ma baa ṣe dide kuro l'ori idọbalẹ.

Irohin fi kun un pe lẹsẹkẹsẹ ni ọkunrin na ti wen pe orukọ rẹ ni Christian Ugwu mu aṣẹ na ṣẹ; ọkan ninu wọn nṣọ ọ, awọn yoku si wọle ọkunrin na lọ lati ko o ni dukia.

Irohin sọ pe, ṣugbọn l'ojiji ni ọkunrin onile yi dide nilẹ, o si fi gbogbo agbara rẹ digbolu ọkan ninu awọn ọlọṣa na ti o nṣọ ọ. Nihin ni ijakadi ti bẹrẹ, ti ọwọ onile si ndun ọlọṣa na karakara. A gbọ pe nigbati ọran na ko wọ mọ ni ọlọṣa na ba fi igbe bọnu.

Irohin fi kun un pe lẹsẹkẹsẹ ni awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti o nfọle lọwọ de, ti nwọn fa ada yọ, ti nwọn si nfi ibinu ṣa a pẹlu ero pe ẹniti o mba ẹlẹgbẹ wọn ja ni nwọn da ada bo laimọ pe ẹlẹgbẹ wọn gan an ni

(Woju ewe kẹfa)

## NI IRANTI

Baba wa ọwọn:



DADDY JOSEPH LANLOKUN LAOṢEBIKAN

ẹni ti o jade l'aiye ni ọjọ kejidinlogun oşu kejọ ọdun 1970 lẹhin ti o ti gbe aadọrun ọdun (90 years) l'aiye.

Eyi ni ọdun kẹrin ti Baba wa oninu rere ti fi awa ọmọ rẹ silẹ lọ si ile aiyeraiye; l'ojoojumọ ni a nṣe iranti rẹ.

"Nwọn ku ninu Jesu, oorun wọn si kun fun ibukun, nwọn bọ lọwọ ẹṣẹ oun 'rora".

Baba-rere, sun ki o si maa sinmi titi a o fi pade ni Paradise.

E. O. LAOṢEBIKAN
(Fun awọn ọmọ ati ọmọ-ọmọ).

# Oyedepo gori itẹ

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni Ṣọhun Ogbomọṣọ Ọba Ọladunni Ajagungbade Kẹta jawe oye le Arẹsa-Adu Irẹsa-Adu titun lori labẹ ayẹyẹ ti o galọla.



ỌBA OYEDEPO EMIOLU
Arẹsa-Adu Irẹsa Adu

Irohin fi ye wa pe ọpọlọpọ enia, ẹlẹgbẹjẹgbẹ, awọn Ijoye ati sanmari ilu Ogbomọṣọ ati ti Irẹsa-Adu, paapaa awọn ẹgbẹ atapako ilu Ogbomọṣọ.

Ninu ọrọ re nigbati o nfi ewe oye le Arẹsa-Adu na lori, Ọba Ajagungbade rọ ọ lati lo ipo rẹ ni rere.

Ninu esi tirẹ, Ọba na dupẹ lọwọ Ọba Ajagungbade, Ijoye rẹ ati gbogbo enia Ogbomọṣọ fun ifẹ inurere ti nwọn ni si i, o si ṣeleri lati mu ki ifẹ ara wa titi.

NI IRẸSADU-ADU

Ninu ọrọ rẹ ẹwẹ nigbati o gori itẹ tan ni Irẹsa-Adu, Ọba Oyedepo dupẹ lọwọ awọn enia re fun ifẹ ti nwọn ni si i paapaa awọn ẹbi rẹ. O ṣe ileri lati lo ipo oun ni otitọ ati ododo, o si kesi wọn lati fọwọsowọpọ pẹlu rẹ.

## ATIORO ỌMỌ ATIALA

# Ma se fara we won [6]

Bi a ba nsọ pe
Aṣebuburu yeye
Ninu ọmọ araiye
O le dabi isọkusọ
Bi a ba nfẹsunkan
Pe, iwa eṣubeleke pọ
Laarin ọmọ enia,
O le dabi ọrọ lasan,
O le dabi isọkusọ;
Ani bi a ba nfẹsun kan
Ti a ko ba ti a dele
gidi
O le mu k'aiye
Maa bu ni l'alakọra.
Nitoripe, oniruuru
Ni iṣe ẹda l'aiye,
Otọọtọ ni iṣe enia;
B'onibajẹ meji ba mbẹ
Ninu ile,
Ohun ti nwọn bajẹ si
Ko nii ṣai yatọ gidi
Oniruuru niwa ẹda
Ti mbẹ l'oke eepẹ.




Nitorina:
Gbogbo janmaa wa,
Ẹ sa f'aṣebi pata
Ti mbẹ ninu aiye,
Ẹ ma ṣe f'iwa jọ wọn,
Ẹ ma huwa
Gẹgẹ bi iṣe wọn.
Ati eyi t'o kere
Ninu iṣe ibi
Ati eyi t'o papọju
Ninu laifi ọmọ enia
Ẹ ma f'iwa jọwa ẹda
Ẹ ma farawe 'ṣẹ aṣebi
Eyi to ba rọsọmu
Ni ẹ farawe
Ninu iṣe ọmọ enia
Ẹ wo ẹni ti a bi lai lọla,
Ẹ wo enia ti a wo
dagba
T'o jẹ atọlẹdọlẹ oṣi
Ti baba ko lowo
Ti iya ko lowo
Ti nwọn fi d'ajule ọrun
Ṣugbọn t'Ọba Odumare
Waa ṣiju aanu wo
T'o sọ di olowo
Pe, ko le gbe
Orukọ awọn obi rẹ yọ,
Ati ko le jẹ ẹkọ
Fun gbogbo atonipin,
T'o waa dẹhin ọrọ tan
T'o ja Aala ni tanmaa!!!
Ani ti o di olowo tan
T'o gbagbe atidide,
T'o d'enia pataki tan
T'o gbagbe atigoke,
T'o waa d'enia nla tan
T'o gbagbe Olodumare
T'o sọ ọ d'enia gidi,
T'o si tun gbagbe
Pe, ninu opijẹ obi
L'oun ti ṣẹ,
T'o wa nhuwa
Bi ẹni pe ajogunba
Ni ipo ọla jẹ fun un.
Ẹ jọwọ bi ẹ ba ri
Iru enia to nṣe bi eyi
Ẹ ye ẹ ma fara we wọn
Nitoripe:
Nigbati nwọn d'enia tan
Nwọn gbagbe idide wọn
Nigbati nwọn ba ri jẹ
tan
Nwọn a gbagbe ipilẹ,
Bi nwọn ba d'enia tan
Nwọn a gbagbe
Aala t'o ṣ'ogo fun wọn,
Nwọn a mẹmu amuju,
Nwọn a maa sọrọ
Bi ẹni pe
Ọgbọn inu wọn
L'o gbe wọn ga.
Nigbati nwọn ba nhuwa
Ẹnu a ya mi titi
Pe, ẹni a ṣe l'oore tan
gbera,
O lọọ f'ọpẹ fun
Ẹni ti nṣe e nibi !!!
Odumare ṣaanu
O s'ọmọ talaka di baba,
O s'ọmọ ẹni lasan di
Ẹni ti nri t'aje ṣe,
O si sọ ọmọ opijẹ
Di mẹgida l'oju muju-
muwa.
Ṣugbọn t'o waa dẹhin
ọrọ
T'ẹni na mu owo
T'o fi njaiye l'ogun:
T'o mu ipo
T'o fi njẹ enia niya;
T'o mu owo ọhun
T'o fi njaiyekaiye
T'o nrubọ f'eegun
T'o npa'bi f'ooṣa,
T'o ndupẹ lọwọ wọn
Pe, awọn l'o gbe 'un ga!
T'o nfẹ hoo bi ọka,
T'o npe onijo,
T'o npe onilu,
T'o nfa obinrin mọra,
T'o ni bi a ba d'enia
tan
Nṣe l'aa yọ gidi!
Kaka k'alakọri ranti ibẹrẹ
Kaka ko ranti
Ọmọ ẹni ti o jẹ,
Kaka ko ronu
Pe, Aala l'o gbe 'un ga
Kaka ko fi osuba
Fun Aala l'Oke
Ko maa huwa rere,
Nṣe l'o nhuwa aitọ
Gẹgẹ bi a ti too soke.
Njẹ gbogbo enia pata
Ti ngbọ nasia yi,
B'Oluwa ṣe nyin l'oore
Ẹ maa dupẹ f'Oluwa,
Ẹ ma f'ọti dupẹ,
Ẹ ma fi ẹjẹ ẹran dupẹ
Ẹ ma f'ijo ọti dupẹ,
Ẹ ma f'ebọ riru dupẹ
Ẹ ma finu yin ni l'ogo
ni,
Ẹ si maa huwa t'o tọ
T'O nfẹ ka hu n'iwa,
Bi ẹ ba r'enia
Ti ko tẹle 'mọran yi
Ẹ ma f'ara we wọn
Ẹni egun ni wọn,
Nwọn ko ṣee fiwa jọ.

ỌLỌLA ATIORO

# Owo nwole fun kiko Aafin Sohun

OJILELẸGBAA o le eejọ Naira (₦2,047) ni Igbimọ atunkọ aafin Ṣọhun Ogbomọṣọ ri lẹsẹkẹsẹ nibi eto ikowojọ ti o waiye ni ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu keje ọdun yi, nibi ipade Ẹgbẹ Ogbomọṣọ Parapọ ti agbegbe Ogbomọṣọ ti nwọn npe ni ẹka ti ile.

A o ranti pe nigba akọkọ ti nwọn ṣe ifilọlẹ ikowojọ na ni ọjọ kẹtala oṣu kẹrin ọdun yi, ọke kan abọ Naira (₦30,000) ni nwọn ri kojọ.

Ọkẹ meji abọ Naira (₦50,000) ni a gbọ pe nwọn yio fi kọ aafin na, ni ọjọ keje oṣu kẹsan ọdun yi ni a si gbọ pe nwọn yio fi ipilẹ ile na lelẹ.

Awọn ọmọ ibilẹ Ibadan ti ngbe ilu Ogbomọṣọ paapaa wa ninu awọn enia ti o da ninu owo na laipẹ yi.

Nigbati o nsọrọ nibi ikowojọ na, Alagba S.A. Idowu ti o ṣe Alaga l'ọjọ na kesi gbogbo ọmọ Ogbomọṣọ lati jaramọ idawo na tọkantọkan ki iṣẹ na le tete bẹrẹ.

Alagba Idowu mu un da awọn enia loju pe ki yio si madaru tabi ki a na kọbọ meji ki a pe e ni kọbọ mẹwa nipa owo ti awọn ba ri kojọ fun eto na.

Alagba M. A. Agbejimi ni Alaga Igbimọ ti ile, Oloye Adegbọla Oyeniran si ni Akọwe.

### ṢỌHUN SỌRỌ

Ninu ọrọ Ṣọhun Ogbomọṣọ Ọba Ọladunni Ajagungbade Kẹta, o ki gbogbo enia ti o nipa nibi idanwo na ku



ỌBA ỌLADUNNI AJAGUNGBADE KẸTA
Ṣọhun Ogbomọṣọ

inawo, o si rọ awọn ti ko ti i da rara ninu ẹka ti ile tabi ti idile lati gbiyanju da tiwọn laipẹ ọjọ.

Ọba na dupẹ gidi-gidi lọwọ awọn enia rẹ fun iwa nini ifẹ si ilu ara ẹni eyi ti o sọ pe o mu ki nwọn maa dawo na.

* Bakanna ni awọn enia na tun ri owo ti o to ọọdunrunlẹ-ẹgbaaji Naira o din ẹẹjọ (₦4, 294) kojọ ni ẹka wọn gbogbo laarin oṣu meji sẹhin ti nwọn ṣe ipade Parapọ na tan ni ọjọ kerindinlogun oṣu kefa odun yi fun eto idaṣẹsilẹ l'abẹ asia eto iranraẹni lowo ti Ijoba Ipinle—Iwo Oorun gbe kale.

Nigbati o nki awon ikọ gbogbo ti o mu owo na wale kuabọ, Amofin Ọlatunji Mohammed ṣalaye pe, pupo ninu eka won ni koi ti i mu owo tire wa tabi fi ranṣe.

O ki awon ti o mu owo na wa, o si ro won lati jabo fun eka won pe iṣe tun ku niwaju won lati ṣe.

Amofin Mohammed kẹdun pe pupọ ninu awọn ọmọ Ogbomọṣọ ti o ti ri jajẹ ni ko lọwọ ninu eto nla na eyi ti o sọ pe o le mu ki ririṣe wa ni ilu.

O ni ninu awọn ilu nlanla ti awọn ko gbe tii ri idawo wọn lehin ipade ti awọn ṣe kẹhin ni ọjọ kẹẹdogun ati ẹkẹrindinlogun oṣu kẹfa ọdun yi ni; Eko, Jos, ati Osogbo.

Ni ipari, Amofin na rọ gbogbo ọmọ Ogbomọṣọ lati jigiri fun ire ati idagbasoke ilu wọn nitoripe :" Ajeje, ọwọ kan ko gbe ẹru d'ori"


## Lucky Jax Book Shop

Njẹ o ti ra iwe ile-iwe ọmọ rẹ fun ọdun 1974—1975?

Bi o ko ba ti i ra a, fun ẹdinwo ati ẹbun ọfẹ:

Tete lọọ ra iwe rẹ ni: LUCKY JAX BOOKSHOP.

Address:- Ile Itawe wa ni o kọju si Office awọn Panapana, Ọjaigbo Street, Ogbomọṣọ.

AKEDE ONA IYE

# E je ki a gbadura (1)

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

"ỌLỌRUN bojuwo ilẹ lati ọrun wa sara awọn ọmọ enia lati wo o bi ẹnikan wa ti oye ye ti o si nwa Ọlọrun, Gbogbo wọn li o si pada sẹhin, nwọn si di eleeri patapata, ko si ẹni ti nṣe rere, ko si ẹnikan"- Orin Dafidi 53, 2--3.

Bibeli sọ pe; "Ọlọrun si ri i pe iwa buburu enia di pupọ li aiye, ati pe gbogbo iro ọkan rẹ kiki ibi ni lojoojumọ. Inu Oluwa si bajẹ nitori ti o da enia si aiye, o si dun un de ọkan rẹ, Oluwa si wi pe, Emi o pa enia ti mo ti da run kuro l'ori ilẹ, ati enia, ati ẹranko, ati ohun ti nrako, ati ẹiyẹ oju ọrun; nitori inu mi bajẹ ti mo ti da wọn".

Ewo ni ko to lati mu Ọlọrun binu ninu gbogbo iwa ọmọ enia? Ọmọ aiye yi ha jawọ ninu oniruuru iwa ẹṣẹ si Ọlọrun Ẹlẹda wọn bi ?

Ọlọrun fẹran ẹda ọwọ Rẹ tobẹẹ ti O ran Jesu Kristi ọmọ Rẹ kanṣoṣo lati wa si aiye ati lati ku fun imukoro-ẹṣẹ ati igbala wa, ọmọ araiye kọ Ọ!

Kaka ki nwọn gba A gbọ, nwọn kọ Ọ. Aiye ni Jesu l'ara. Awọn Olori Alufaa ati awọn Agbagba ti o yẹ ki nwọn tun ọna ṣe niwaju Jesu, ọta ni nwọn gbe dide si I. Ẹda tun nti inu ẹṣẹ bọ sinu ẹṣẹ !!

Ọmọ aiye yi njọ araa wọn l'oju nipa imọ asan aiye yi, nwọn si titori eyi dẹṣẹ nigbagbogbo. Lati fi ara ẹni fun aiye yi pẹlu ohun asan inu rẹ jẹ dida ẹṣẹ nigbagbogbo, eyiti iṣe ṣiṣọtẹ si Ọlọrun Ẹlẹda wa.

Ẹ jẹ ki olukuluku enia ṣọra pẹlu iwa rẹ gbogbo ki a ma si ṣe mu Ọlọrun Ẹlẹda wa binu. Ẹ maa tẹle ifẹ Oluwa pẹlu ẹmi irẹlẹ, ki ẹnikẹni ma si ṣe jọ araa rẹ l'oju, tabi ki o ma ro pe aṣiṣe kọja oun.

Nitorina ara, bi ẹ ba ri iṣina niwaju enikan, ẹnyin ti o ku, ẹ ma ṣe fi i ṣe ẹlẹya, ẹ mura lati fi apẹrẹ iwa rere tiyin tọ ọ sọna.

Ẹ si maa kun fun adura nigbagbogbo ki ẹ le maa rin ọna tootọ ti Ọlọrun Baba nfẹ ki ẹ rin ki ẹ baa le ṣe ifẹ Ọlọrun ni aṣeyege.

Nitọrina, mo npe enyin enia inu aiye si ipe adura ti ng o fi ọsẹ mẹta ṣe lati ọsẹ yi lọ:

ADURA

Oluwa Ọlọrun Olodumare t'O da aiye ati ọrun, emi aworan Rẹ npe Ọ nisisiyi, jọwọ Oluwa, waa gba ọpẹ ati iyin mi ki O si gba gbogbo ero mi ni rere wọle si'ọdọ Rẹ ki awọn Angẹli Rẹ le jẹ oluṣọ mi ninu aiye na ti Iwọ Oluwa ti ri pe ogun eṣu pọ yi.

Oluwa, bi o tilẹ jẹ pe aiye ti ṣẹ lati ibẹrẹ ọjọ nipa eyi ti ADAMU ati EFA mu iṣina ba aiye, jọwọ Oluwa, mu aṣiṣe awọn enia ibẹrẹ ọjọ kuro l'ori mi ki ng ma baa parun pẹlu awọn onisẹ ẹṣẹ.

Ani, Oluwa mi, gbogbo ohun rere ti a nṣe ninu aiye ni ọta ikọkọ ndọdẹ rẹ lati ba a jẹ toripe aiye ni baba wọn ti iṣe eṣu wa. Torina Oluwa, pa eṣu l'ẹnu mọ ati awọn ọmọ ogun eṣu ki nwọn maṣe ba iṣẹ mi jẹ.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu naa

Oluwa, jọwọ ba mi fun awọn Olori wa gbogbo ni ọgbọn, oye ati imọ ki nwọn le maa ronu pe awọn enia ti iya njẹ ni nwọn nṣe Olori fun.

Oluwa, mu awọn ti o nṣe iṣẹ ẹṣẹ ronupiwada kuro ninu ẹṣẹ wọn, ki O ma si ṣe jẹ ki olododo maa ba ẹlẹṣẹ ṣiṣẹ ibi pọ ki ibajẹ ma baa tubọ maa gbilẹ l'orilẹ - ede wa.

Oluwa, ki ọrọ Rẹ gbilẹ l'ọkan awọn Olori wa gbogbo tobẹẹ ki ẹmi ifẹ wọnu wọn lati maa wa ọna bi awọn ọja rira wa yio ṣe jẹ ọpọ ati irọrun ki ara le dẹ awọn ẹni ti o ku diẹ kioto fun l'orilẹ - ede wa.

Oluwa, kọ mi lati le maa ronu nipa igbesi aiye t'o ti kọja, eyi ti o yẹ ki o jẹ ẹkọ fun mi; paapaa, lati maa ronu nipa ognnlọgọ ẹlegbẹ iruu mi ti nWọn ti ba ogun lọ ti nWọn ko si ni anfani lati wa laaye ni akoko yi lati le maa le ohun asan aiye, eyi ti ko nii ṣai ba aiye lọ.

Nitoripe, ọjọ mbọ ti a o sọ pe, "Maa bọ" lai nii le wojumọ ọrọ aiye yi mọ. Oluwa, paṣẹ fun Aiṣedeede ti iṣe aisan ara lati jade kuro ninu agọ araa mi ki ng le maa fi ara ti o yẹ ninu alaafia yin Ọ.

Oluwa, ma ṣe gba fun ile jijo, ati agbara ojo lati ba ohun ini wa jẹ ni Orilẹ - ede yi. Oluwa, jọwọ fi agogo iye Rẹ pe otitọ ati ododo sinu mi lati le maa ṣiṣẹ mi gbogbo pẹlu idaniloju ati igboiya l'ori otitọ. Ki ng ma ṣe gba imọ enia buburu l'ookan aiya mi nitori JESU KRISTI ỌMỌ RẸ OLUWA WA Amin.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,916 James Fatunmbi, Ibadan
10,917 Sunday Asi--gbonlusi, Abeokuta
10,918 Musiba Adeṣẹgun, Abẹokuta
10,919 Mallam Tairu Imam, Kabba
10,920 Olufẹmi Kọla--wọle, Ijurin--Ekiti
10,921 Akimu Ololade Raji, Eko
10,922 Ọlasupọ Owo--tunde, Ada
10,923 G. A. Ọlaniyi, Ogbomọṣọ
10,924 Edintọn Adedokun, Ejigbo
10,925 J. A. Yusufu, Ogbomọṣọ
10,926 E. O. Ọyawale, Ibadan

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI
**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ____________

Adirẹsi rẹ: ____________

Ọmọ ilu ti o jẹ ____________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

## IWE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:
1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ,
Box 1206,
Ibadan.



AWORAN ẹgbẹ yi nṣe afihan Ọbabinrin ilẹ Gẹẹsi Alaiyeluwa Elizabeth keji bi o ti nfi ẹwọ ṣa ẹṣin ere ije rẹ ti njẹ Highclere lara, ti o si nki ẹni ti o gun un Joe Mercer ati Mekiwo rẹ Dick Hern lẹhin ti ẹṣin na sare ije kan ni ilu Chantilly nilẹ Franse, ti o si gba ipo kinni, eyi ti yio mu ki Ọbabinrin na gba ẹgbẹrun pọnu ati ẹgbẹrun ṣile.

# Koledowo komo

NI Ilọlọ yi ni Ọgbẹni Ganiyu Lasisi Koledowo ati aya rẹ Iyaafin Salọmọtu Adunni Koledowo fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ l'ọrun nibi ajọyọ ikọmọkunrin kan ti Ọlọrun fi ta ìọkọtaya na l'ọrẹ. Ni Oke Laka, Ogbomọṣọ ni ayẹyẹ na ti waiye.

Amusa Ajao Koledowo ni nwọn sọ orukọ ọmọ na. Awọn enia lati ilu Oṣogbo paapaa wa sibi ikomọ na.

Awọn oṣiṣẹ ile ẹjọ Ibilẹ l'Ogbomọṣọ, awọn Onṣowo, Oiukọni, awọn aṣiwaju ẹsin Musulumi ati bẹẹbẹẹ lọ pẹlu wa sibi ikomọ na.

Diẹ ti aaye wa fun lati darukọ ni Ọmọ Ọba Nkanlọla Layọde, Ọgbẹni B. A. Adebiyi, Saliu Aiagbe Paakoyi, Arabinrin Raliatu Odee; Rafatu Arikẹ, Lasisi Koledowo, Oyeniyi Ajani, Jimọ Adeyẹmọ, Afọlabi Ọlalẹye, Jacob Awotunde, Alhaji Sunm nu Akintunde, Aminatu Oyelude, Asanatu Oyelude, Sikiratu ati Ọwẹyọ.

# Alafowosowopo Oyan

NI ọjọ karun oṣu kẹjọ ọdun yi ni apapọ Ẹgbẹ Alafọwọsowọpọ mẹjọ ti o wa nilu Ọyan l'agbegbe Ọṣun ṣe ipade ọlọdọọdun wọn nilu na nibiti Ọgbẹni Ifẹdayọ Adejare ti fi iwe aṣẹ fun Ẹgbẹ Alafọwọsowọpọ ti njẹ Alaafiatayọ ni Ọyan.

Ẹgbẹ na ni N1,534 lọwọ, nwọn si jere Naira mẹtalelogofa. Ṣugbọn Ọgbẹni G. G. Abioye ti iṣe Akọwe Ẹgbẹ na l'aapapọ ṣe ileri pe owo ti ọmọ Ẹgbẹ kọọkan yio maa da yio gbera lati Naira marun si mẹwa ki bukaata Ẹgbẹ le maa biiya si i.

Awọn Alaga awọn Ẹgbẹ ni: E. S. A. Oriolowo fun Alaafiatayọ, Jacob Ogunkalẹ fun Aiyemidire, E. A. Ọtọlorin fun Abọdedayọ, J. Ọkẹ fun Kajọla, Sule Olowola fun Akorede, Amos Adeyemi fun Amuludun, J. Ọmọtọṣọ fun Irewọlede, ati Julius Akanji fun Ireakari.

# Sikiratu Tẹla rele oko

IROHIN lati ilu Ọyọ fi ye wa pe ọkan ninu awọn ọmọ ọba ni ilu Ọyọ ti orukọ rẹ njẹ Sikiratu Tẹla ti ile Gbenku, Apinni, Ọyọ, ti lọ sile ọkọ labẹ aṣa ibilẹ awọn ọmọ ọba Ọyọ.

Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu keji ọdun yi ni ọmọ ọba Sikiratu lọ sile ọkọ na. Alufaa Kelani Ogbomọṣọ lo ṣeto isoyigi ni ilana ẹsin Islam.

Baba ọmọ na Ọmọ ọba ati iya rẹ Alhaja Alimọtu Tẹla na baba-nla owo nibi ayẹyẹ na nitoripe o tẹ gbogbo alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun nipa jijẹ ati mimu.

Ki o too di pe nwọn sin ọmọ na lọ sile ọkọ rẹ Ọgbẹni Ganiyu, o wọ aṣọ ọkunrin gẹgẹ bi aṣa awọn ọmọ ọba Ọyọ ti o ba nlọ si ile ọkọ; gbogbo awọn Ayaba lo ṣe oro igba ṣiṣi fun un pẹlu. Ayẹyẹ na dun pupọ.

Awọn ẹlẹgbẹjẹgbẹ ati enia lati ilẹ Franse, ilẹ Hausa, Ọyọ, ati Ogbomọṣọ lo pesẹ sibẹ. Ara wọn ni Limọta-Siẹ, Mualim Alaofẹ, Alufaa Moyọsọrẹ, Wosilatu Adukẹ, Ṣifawu Abikẹ, Safu, Rali ati Ganiyi Tẹla.

## Jovial Nap

WEEK 3,
NAP 5, 15, 39.
Perm 1, 2, 15, 16, 18
If Millwall draws come for 3 sure draws in Week 4.

M. O. Oketona,
15 Oke Ọla St
Apomu — Ikire.
5xxbk

13

## 17


IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurnni esu marun Yoruba 55k
   Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k)
   Iwe Eniaṣoro (50k)
7. Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (N1.5)
    Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a. Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin.


## Ijinle Owe Yoruba

(Fun ẹni ti nfẹ Ọgbọn, Oye, ati Imọ (8) lati ọwọ lawuyi ogunniran

71. Eke f'ete tu'le
    Ofofo f'ẹnu tu'bi
    Ẹga kọle f'ẹnu tu u !
72. Elubọ ṣe egbodo ri
    Arugbo ṣe ọmọge ri;
    Mariwo ti nñgbago ṣẹsin nkọ?
    Oun paapaa mbọ wan d'agbelẹbe.
73. Enia meji ni Ọlọrun kọ:
    Eni t'o ṣẹ ti ko bẹbẹ.
    At'ẹni ti a bẹ ti ko gbọ.
74. Eṣu ko si l'ori, inu l'eṣu wa.
    Ibi'ri kan ko si,
    Inu ni maa bi'ni.
75. Ewu ni ogbo, irungbọn l'agba
    Tubọmu ni ti afojudi.
76. Egungun ko mọ'yi aṣọ
    Gbongbo ọna ko mọ'yi ẹsẹ
    Ẹni ti nkosun
    Ko mọ'yi ẹni ti nkun ata.
    Ẹni a bi l'Eko ko mọ'yi
    Ẹni a bi l'oko.
77. Enia ki i jẹ meji l'aba Alade:
    Ẹni ba jẹ'ṣu ko nii mumi,
    Ẹni ba mumi ko ni i jẹ'ṣu.
78. Enia tan 'raa rẹ jẹ bi Iya Ibeji:
    Nwọn ni, "Ọmọ rẹ kan yoku nkọ?"
    O ni, "O lọ s'Eko!"
79. Esuru ṣaṣeju, o tẹ lọwọ oniyan,
    Kuku-nduku dun adunju
    O kọ ile ana ko lọ.
80. Eyi, "Ọmọ ẹgbọn",
    T'ọhun "Ọmọ aburo",
    Ko si ohun t'o dun
    Bii "Ka bi t'ẹni."


## ANFANI FUN O

Kinni iṣoro rẹ? Kini edun ọkan re? Kini o nru o loju? iwọ ha nlalakala bi? Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli bi?

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ye ọ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ pẹlu address rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi.

Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiye lọwọ.

Kọwe si :
Woli S. I. Owoẹyẹ
N6/763A Kabiawu Street,
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ
"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi" Orin Dafidi 34, 2

# KI LO SELE ?

## Gbenle sile Itura

OLOYE Arẹ Phillip Gbenle, Onișowo pataki kan ni ilu Eko ti și ile itura asiko titun kan ti nje IFẸLODUN HOTEL, si ilu rẹ Ijọmu-Oro ni ekun Igbomina/Ekiti ni Ipinlẹ Kwara.

Irohin fi ye wa pe, esẹ awọn ọtọkulu kaakiri ilẹ Naijiria ni o pe sibi ayẹyẹ șiși ile Itura na eyiti nwọn și laipẹ yi labẹ Alaga Balẹ Ijomu Oro, Oloye Orimadegun.

Ninu ọrọ rẹ, Baalẹ Orimadegun kan saara si Arẹ Phillip Gbenle fun ifẹ ilu abinibi ẹni ti o ni lọkan ti o mu lati ro iru ișẹ rere bayi si ilu rẹ.

O ni nitori Ile Itura jẹ ohun amuludun ati afa ero wọ ilu. O ni bi ilu kan ba ti ni ile itura si ni awọn arinrinajo ati onișowo lati ibi gbogbo yio ti maa rọ wọ ilu si, nitori ohun ni o mu ọkan wọn balẹ pe nwọn yio ribi wọ si tabi gbadun diẹ lẹhin rira tita wọn ki nwọn to pada si ibugbe wọn, eyi yio si maa mu owo ati ișẹ aje ilu gberu si i

Ni ipari ọrọ rẹ, Baalẹ na dupẹ lọwọ Alakoso ile Itura na Arẹ Gbenle fun ohun manigbagbe ti o șe na.

Ki ayẹyẹ ọjọ na to bẹrẹ Alufa Agba Ijọ Aguda ni Ijomu-Oro ni o șe akanșe adura ki awọn Odẹ ilu na too șe tiwọn. Nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na l'ọrun.

Lẹhin ayẹyẹ na ni ọja tita bẹrẹ ni ile itura Ifẹlodun Hotel na, eyiti pupọ ninu awọn alabașẹyẹ ọjọ na si ba wọn ra ọja.

Gbogbo awọn ẹbi Oloye Arẹ Gbenle ni nwọn pejupesẹ sibi inawo ọjọ na. l'ara wọn ni Amos Gbenle, A. K. Karimu Gbenle, Alhaji Bello Gbenle, ati Ọgbẹni Abikoye.

## Abajade Idanwo Bibeli

LATI ỌWỌ J. K. KOBIOWU

IWONYI ni orukọ awọn enia ti o șe daradara ninu Idanwo Bibeli ti o jade ninu Imọlẹ Owurọ 27/7/74:

Matteu Olaoye lati Oșogbo, Dauda Alabi lati Ibadan, James Awotoye lati Ijara, Pastor J. O. Yamakinde lati Ibadan, Titus Awopeju lati Ilesa, Apostle S. A. Babatunde lati Ibadan;

Gbenga Ọladejọ lati Eko, Jacob Oseni lati Ibadan, Hesekiah Opadere lati Eko, Michael Ojo lati Ibadan, S. O. Rainbow lati Ogbomoṣọ, S. K. Oyewọ lati Ibadan, Isaac Ọgunni lati Mușin;

Olurẹmi Adeniyi lati Ibadan, Confort Layẹni lati Ebutemẹta, James Akande lati Șomolu, Lydia Aarinọla lati Ibadan, Emmanuel Asorolu lati Ilọrin, Joseph Fakayọde lati Arandun, J. O. Oyekọla lati Ibadan;

Peter Falọla lati Ọyọ, Dorcas Adeyẹmọ lati Ibadan, J. A. Ayọade lati Ogbomọșọ, Abioye Oyekanmi lati Ibadan, J. O. Ojoșọla lati Șomolu, Filișia Ọladokun lati Ogbomọșọ; Moses Ọjẹlade lati Ibadan, Joseph Ọlajide lati Eko, J. O. Ajao lati Ọkaka;

David Arẹmu lati Ogbomọșọ, Mrs. C. A. Belo lati Ibadan, M. G. Ajagbe lati Surulere, Lean Ayọrinde lati Ibadan, Evan. Olu Daniel lati Ibadan, Joseph Adepoju lati Ibadan, M.A. Akanni lati Kano gba mẹwẹẹwa. Olubi lati Ibadan gba marun.

IDAHUN IBEERE

Iwonyi ni itọkasi idahun awọn ibeere na.

1. Efesu ori 5 ẹsẹ 18
2. Efesu ori 4 ẹsẹ 28
3. Efesu ori 4 ẹsẹ 25
4. Efesu ori 4 ẹsẹ 19
5. Efesu ori 5 ẹsẹ 20
6. Efesu ori 6 ẹsẹ 10
7. Efesu ori 6 ẹsẹ 18
8. Efesu ori 5 ẹsẹ 21
9. Efesu ori 6 ẹsẹ 11
10. Efesu ori 4 ẹsẹ 32

IDANWO TITUN

1. Kini Esra sọ nipa Aafin ?
2. Kini Kronika sọ nipa Aafin ?
3. Kini Esteri sọ nipa Aafin ?
4. Kini Isaiah sọ nipa Aafin ?
5. Kini Solomoni sọ nipa Aafin ?

Ẹ tete fi idahun nyin pẹlu titọkasi Bibeli ranșẹ si:
Jọșua Karimu Kobiowu
(Onidanwo Bibeli)
S2/81 Ọranyan Street
Ibadan.

## Alagba Scott jade laiye

NI ibẹrẹ ọsẹ yi ni a gbọ irohin iku Alagba Erastus Babatunde Scott ni ilu Eko.

Oloogbe Scott nigba aiye rẹ ni Alakoso ile itaja oogun olokiki ti njẹ "WATERLOO MEDICINE STORES" ti o wa l'Opopo Palm Church - Ita Faji, Eko.

Ninu ile rẹ ni 7, Scott St. lẹba Mọșalași Jimọ Eko ni ologbe na ku si. Ẹni aadọrin ọdun (70yrs.) ni nwọn pe oloogbe na.

Ọmọ mẹsan ati ọpọlọpọ ọmọ-ọmọ ni o gbẹhin Oloogbe na. L'ara wọn ni Ọgbẹni Ẹnilọ Scott, Ọga kan ni ile - iwosan nla Eko, Nọọsi Yeside Scott, Ọlabisi Scott, (London) Ademọla Scott, (Ọga Kongirakitọ) Olufunkẹ Scott, Adeniyi Scott (ti N. P. A.) Ọmọ-ogun Adekunle Scott ati Ọgagun Ọlașeni Scott.

# IWE SI OLOTU

## Ijamba moto

Olootu,

NIGBAGBOGBO ni awa ọmọ Naijiria maa ngbọ irohin pe nșe ni ijamba mọto ti o ngba ọpọlọpọ ẹmi npọ si i ni awọn oju ọna wa.

Awọn awakọ nikan ni a saba maa ndi ẹbi ru nitori iwa aibikita ọpọlọpọ wọn.

Șugbọn, okunfa ijamba mọto miran ti o dabi ẹni pe awọn Alașẹ ko mọ, tabi ti nwọn ko kọ ibi ara si lati dẹkun ni kiko yanrin ati okuta si awọn oju ọna ilu nlanla wa paapaa julọ IBADAN.

Mo nkesi ile ișẹ Ọlọpa Naijiria lati so igba agbejẹẹ mọ awọn ti o nhu iru iwa yi lẹwọ nipa pipe ẹnikeni ti o ba ko yanrin si oju titi l'ẹjọ, ayafi ile ișẹ alagbașe ti o ba ntun ọna șe lọwọ ni ki nwọn ma șe ba șejọ.

Laișe aniani, eyi yio din ijamba mọto ku, ọkọ yio si le maa lọ geerege l'oju ọna ni igboro.

Emi ni,
Adelani Akintunde,
Ibadan.

## Kolekole enia dudu dara

Olootu,

Ninu Imọlẹ Owurọ 3 : 8 : 74 ni Ọgbẹni kan Kọla Lawal lati Eko nkesi awọn Igbimọ kikọ aafin fun Olubadan Ibadan pe ki nwọn mașe gbe kikọ aafin na fun kọlekọle enia dudu bikoșe alawọfunfun nitori o pe enia dudu ni alaidara.

Emi ko ro pe iru ero bayi dara rara nitoripe ọpọ enia dudu wa bi Harbony Ltd; L. A. O Bamjoko & Sons, L. A. Odunjọ, J. F. Ọsọsami & Sons, Alhaji W. O. Lawal & Sons, I. A. Olunlọyọ ati bẹẹbẹẹ lọ lo mọ ișẹ ju awọn alawọ funfun lọ

Nitorina, ko yẹ k awa araa wa maa foju tẹmbẹlu araa wa, bẹẹni ko si yẹ ki a maa huwa l'ọna ti a o fi maa di ẹlomiran l'ẹnu ișẹ. Awọn kọlekọlẹ dudu na dara o.

Emi ni,
S. M. Oyekale,
Ibadan.

## ATIORO, MAA BU WON

Olootu,

Mo ranti pe Ọlọla Atioro ọmọ Atiala Baba Atiẹlẹ ki i fi oju awọn ọlọmoge balẹ nigbakan bi nwọn ba ti nhuwa ti ko dara.

Șugbọn iwa buburu ti nwọn nhu bayi ti pọju. Boya nitoripe Atioro ko bu wọn mọ ni. Nitorina, Atioro, maa bu wọn daadaa ki nwọn mașe ba aiye jẹ fun wa o.

Șugbọn mo fẹ ki o da ọ l'oju pe, ki o mașe bẹru, mo mbẹ lẹhin rẹ, bi o șe ile ẹjọ, bi o șe ile Ọlọpa ati ibikibi.

Emi ni,
Atanda Afariẹnigọșogun,
Oșogbo.

**Toyin Bookshop**

FUN ẹdinwo ati ẹbun ọfẹ, waa ra iwe rẹ ni : TOYIN BOOKSHOP,
Takie Sq,
Ogbomọșọ.
Phone 90.

# Iwe Orire titun waiye

NI ọjọ kẹwa osu kejọ odun yi ni Ọgbẹni Akinboro ti iṣe Oludari ile iṣẹ kan ti orukọ re njẹ Universal Tips & Co (Nig) ti adugbo Oniyere Aperin Ibadan ṣe ayẹyẹ ifilọlẹ awọn Iwe Orire meji ti orukọ wọn njẹ Jack Pot "999" ati Stakers Informant Nap ninu Gbọngan Mapo nilu Ibadan.

Ninu ọrọ tirẹ, Ọgbẹni S. O. Ọlaniran ṣe alaye nipa ere idije tẹtẹ ti alawọfunfun, fun awọn ti o wa sibi ayẹyẹ na, o si ka awọn ofin ati ilana ti awọn oluta tẹtẹ gbọdọ maa tẹle bi nwọn ko ba fẹẹ padanu owo wọn.

Lẹhin na ni o darukọ awọn ayo meji yi. Burnley "Wolves ati Cardiff Oxford. O mu un da awọn Oluta tẹtẹ l'oju pe ọkan yio wọle ninu rẹ.

Ki nwọn too kuro nibẹ, nwọn ta ninu awọn apo iwe asọbade na.

# Ọlosa fi esu se Araa wọn

(Lati oju ewe kinni)

awọn nsa.

Siwaju si i, irohin sọ pe nwọn ti ṣa ẹlẹgbẹ wọn na ni iṣakuṣa ki nwọn too fura pe nṣe ni takute awọn ta s'odi; ati pe nigbati nwọn gburo pe Ọlọpa sunmọ tosi ni nwọn kan lu—'gbo lai r'oju gbe ẹlẹ—gbẹ wọn na ati dukia ti nwọn ti jiko lọ.

A gbọ pe awọn Ọlọpa Onisa ti gbe ọkunrin tihin lọ sile iwosan fun itọju, nwọn si ti fi Ọlọpa ti i nibẹ lati maa ṣọ ọ, nwọn si ti da Ọlọpa inu sita lati ma wa awọn ẹlẹgbẹ rẹ yoku kiri.

Bayi, awọn enia agbegbe na ti bẹrẹ si i lọọ kan saara si ọkunrin onile na fun iwa akin rẹ.

## Ojo Adisa Naps

2 Banker (*1, 2, 3*)

Gbogbo ẹnyin ti ẹ ra 3Bkxxxxs lọwọ wa ni wk 2, ẹ ku orire, mẹta miran tun nbọ ni wk5. Tete fi N5 ranṣẹ si:

Ojo Adisa
N4/273 Ade ọyọ
Oje Rd, Ibadan.
(8&9 1, 2, 3,)

KANISURU NAP
N4/453A Yemẹtu
Aladorin Ibadan
Pair 11&15
Pair 29&52,

# KI LO DUN TO YI?

## Awo

GENERAL PRINCE ADEKUNLE NI

EYI ni lati sọ fun gbogbo enia pe, Ile-Iṣẹ IBUKUN ORISUN IYE RECORDS, ti gbe awo rẹkọọdu nla oloyinmọmọ kan ti gbajumọ Olorin Ọmọ Ọba Adekunle (General Prince Adekunle) ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti njẹ WESTERN BROTHERS BAND, ṣe fun iranti ayẹyẹ idagbere alarinrin kan ti awọn ti nfẹ tirẹ ṣe fun un ki o too lọ si ilu Ọba.

Awo rẹkọọdu nla na pabambari o le gongo oyinmọmọ ado ni. Orin agbọkọgbọn, Jita ati ilu asiko inu rẹ ko ṣee fi ẹnu sọ. Gẹgẹ bi ẹnyin na ti mọ, ojumọ kan orin kan ni ọrọ Adekunle.

Gbogbo enia ni o ti ndu awo na ra bi akara gbigbona. Nitorina tete lọọ ra tirẹ l'oni. O wa kaakiri awọn ile itaja rẹkọọdu ni orilẹ-ede yi" tabi lọdọ:

IBUKUN ORISUN IYE STORES,
77, Herbert Macauley St;
Ebutemẹta,
Lagos. Phone 48340.

# 30 & 31

# Ipade Olosan Ona Oyo

EYI ni lati sọ fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ Ọlọsan ni ọna Ọyọ, Ibadan pe ipade Ẹgbẹ wa ni Gbọngan Agbaje ni ilu Mọniya ni agogo mesan owurọ ọjọ Satide oni (17/8/74). Gbọgbo Ẹgbẹ l'ọkunrin l'obinrin ni a pe o.

Alaga — Alhaji Busari
Akowe — Alufaa Salawu
Iya Ẹgbẹ — Saratu Ayinkẹ
Akapo — Saka Agbeniga
Akọwe Akede — Alhaji Yinusa
Apaṣẹ - Alufaa Usuman Akinyẹle

# NAP 13 15 43

## Goodwill Magic Nap

4 draws to produce 3: Niger Nos 11, 18, 30, 38.

Chief bk Nos 11xxxb draw, Hot pair 30&38 3 draw as from Wk 4 cost N3. 50.

Write the Manager,
E. J. Tuoyo,
Nw2/594
Amugbekun's Comd.
Idikan, Ibadan.

# PAIRS 1&2 8&9



AWORAN wo ni ti ẹgbẹ yi o? Kini awọn melo nṣe nibẹ? Aworan na jẹ ti awọn alare ilẹ Gẹẹsi ati ti India nibi are alafigiṣe kan ninu eyi ti ilẹ Gẹẹsi bori.

Wo aworan na dadadara ki o si ri i bi nwọn ti nṣere na ati bi Ọga ẹlẹgbẹ ti ilẹ Gẹẹsi kan Mike Denness ti nawọ iṣẹgun soke pẹlu ayọ nla.

1 - 4 x ? x 8 x ? ?

# Akiyesi Pataki Fun Onkawe Ogbomoso

EYI ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin Onkawe wa ni ilu Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ pe Ọgbẹni John Bamidele ti aworan rẹ wa l'ẹgbẹ yi ni Onirohin wa fun Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ-oun nikanṣoṣo ni a si nfẹ ki ẹ maa ba fọwọsowọpọ l'ori iṣẹ na.



JOHN BAMIDELE
Ogbomọṣọ

Nitoripe ọpọ igba ni irohin nde si etigbọ wa pe awọn onijẹkujẹ kan ti nwọn nfi araa wọn pe John Bamidele nlọọ gba owo kiri lọwọ awọn enia nitori ki irohin wọn baa le jade ninu Imọlẹ Owurọ.

Nitorina ni a ṣe tẹ aworan John Bamidele tiwa jade pẹlu akiyesi yi ki ẹ baa le mọ Bamdele tootọ ati aiyederu Bamdele nigbakigba ti nwọn ba de ọdọ nyin.

Ẹ wo aworan oke nni daadaa, John Bamidele na ti iṣe aṣoju wa kọ pele, enia pupa ni, ko gunju bẹẹni ki iṣe kurumbete, Agbo Ile Foye, Papa, Ogbomọṣọ ni o si ngbe. Oun ni Onirohin wa tootọ.

—OLOOTU

Printed and Published by The People's Star Press Ltd, N4/496B Yemetu Aladọrin P. M. B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunnira